2 8 FEB 1966


# IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ORẸ AIYE TẸNI GBOGBO LAWA

NO 1,695 FRIDAY, FEBRUARY 11 1966 (2D)


## Ọlọpa Mu Ọlọpa

IBADAN:- Ninu irohin kan to de ile iṣẹ wa ni ọjọ ọjọ 'Ru ti iṣ ọjọ kẹsan osu yi ni irohin na ti fi ye wa pe awọn Ọlọpanu ti mu awọn ọga agba ọlọpa mẹta ni ilu Ibaduu ati pe ọkan ninu awọn ọga ọlọpa na si wa ninu agbadi nla nigbati uwọn mu lọ si Tesau awọn ọlọpa nu lati wa ṣe alaye ti ọnu rẹ lori ẹsun kan ti awọn ọlọpa nu na fi kan.

Ko si pẹ pupọ ọkan ninu awọn ọlọpa na tun wa ninu mọto ayọkẹlẹ ti o si lọ si Tesan awọn ọlọpa nu ni olu ile iṣẹ wọn ni ilu Ibadan lati lọ ṣe alaye ti ẹnu rẹ lori ẹsun ti awọn ọlọpa nu mu awọn ọga agba awọn ọlọpa na fun.

Bakanna ni irohin tun fi ye wa pe ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kẹfa oṣu yi ni awọn ọlọpa nu tun lọ si ile igbakeji Ajẹlẹ awọn ọlọpa ti Ipinlẹ Iwọ Orun gi Ibadan eyiti nwọn si lọ ṣe ayẹwo ile nigbakeji Asele awọn ọlọpa na.

WO OJU EWE KẸFA

# ṢANGBA FỌ! ỌLỌPA RI BỌMBU NI'LE MINISTA

IBADAN:- Sangba fọ, orọ behin yọ, Gbogbo awọn enia ti nwọn wa nibi ipade awon oniwe Irohin ti Ọgbẹni Olufẹmi Olufunwa, enitl iṣe Ọga agba fun awọn olọpa Ipinle Iwọn Orun Naijiria sọ fun awọn oniwe Irohin wipe, awọn ọlọpa ti r Ibon, ẹta Ibon ati etu ninu ile awon Minista kan ti nwon ti fi igbakan jẹ Minista ninu Ijọba Iwọ Orun tẹlẹ ri ni ana ojọ ọjọ 'Bo ti iṣe ojo kẹwa oṣu yi.



Ọgbẹni Edet

Ọga Agba Awọn Olọpa



Ogagun Aguiyi Ironsi

Olori Ijọba Ologun Ilẹ Naijiria

etu ninu ile wọn wipe, ki gbogbo wọn tete yara lọ gbe ibọn wọn fun awọn Olopa ni Tesan kiakia bi nwọn ko ba fẹ pade agba'ko lọna.

Irohin fi ye wa wipe, gbogbo awọn enia ti nwon ri ibọn na lọwo won ati awon ti nwon tun ri bombu ninu ile won ni awon olopa ti mu gbogbo won lo si Tesan. Ọga agba awon olopa na tun se alaye fun awon enia ti nwon wa si ipade awon oniwe Irohin na ni ana wipe gbogbo awon enia ti awon olopa ri ibon ati ota ibon ati bombu ninu ile won wonyi Minista ni nbo gbo won ninu Ijọba Ipinlẹ Iwo orun Naijiria ti Ijọba ologun ti da duro

Sugbon nigbati ọkan ninu awon oniwe Irohin na bere ni ana wipe awon fẹ lati mo oruko awon Minista ti awon olopa na ti ri ibon ati bombu ninu ile won' Ogbẹni Olufunwa so wipe on ko ti n' so orako awon enia na nisisiyi.

Ṣugbon o se ileri fun gbogbo awon oniwe Irohin ti nwon wa si ipade na ni ana wipe, nigbati a ba ko ba to gbogbo aiye ni nwon yio gbo oruko awon Minista na.

A gbo wipe lati igbati awon olopa ti mu awon Minista na ni nwon ti ko gbogbo won lo si Tesan awon olopa nwon ko si gba iduro fun awon Minista na rara.

A gbo wipe, awon Olopa ti kilo fun gbogbo awon Minista ti nwon ba tun ni bombu ninu ile wipe, ki gbogbo won tete yara lo gbe won fun awon Olopa, nitoripe, olopa ko tun gbodo ri Bombu lowo tabi ni ile Minista kankan Minista ti awon Olopa ba ri ibon ninu ile rẹ nwon yio mu oluware gẹgẹbi oda ran tabi arufin.

A lero wipe gbogbo awon Minista ti awon Olopa ri Bom bu nu ile wọn ni nwọn yio farahan niwaju Ada jọ ni owurọ yi lati sọ ti ẹnu wọn ati nibiti nwọn gbe ti ri bọmbu ti awọn Ọlọpa ri lọwọ wọn.

Ọrọ yi ni Ọgbẹni Olufunwa nba awọn Oniwe Irohin sọ ninu ipade kini ti yio kọkọ ba awọn enia na ṣe ni Ibadan ni ana.

O tun sọ siwaju ninu ọrọ rẹ wipe awon Ọlọpa ti tun bẹrẹsi wa iau ile awon Minista miran kakiri lati gba gbogbo ibọn ati ọta ibọn pẹlu ẹtu ti o ba wa lọwọ awọn enia na.

Oga agba awọn Olopa na tun sọ ninu ipade awọn oniwe Irohin eyiti o ṣe ni ọsan ana wipe, awọn Olopa ti kilo fun gbogbo awọn enia ti nwọn ti fi igbakan jẹ Minista ninu Ijọba Ipinlẹ na eyiti wọn ti tuka nisisiyi wipe gbogbo awọn enia tabi awọn Minista ti nwọn ba ni ibọ, Bombu, ọta ibọn, ati

Ni ipari ọrọ rẹ rẹ. Ọgbẹni Olufunwa sọ fun awọn Oniwe Irohin wipe gbogbo awọn ọlọpa Ijọba Ibilẹ ti ijọba ti gbe ibon fun lati ẹhin wa ni o ti gba ibọn lọwọ gbogbo wọn nisisiyi, ti awọn ọlọpa na ko si tun ni ibọn lowọ mọ.

Onirohin wa kan ran wa leti wipe ni opin ọsẹ ti o kọja lọ yi ni awon ọlọpa mu Minista mejeji kan ni Ipinlẹ Iwo Orun Naijiri ti gbogbo awon Minista na si wa ni ogba awon olopa ni Agodi nisisiyi

WO OJU EWE KẸFA

# IWA AGBERE ATI PANSAGA LO FỌ IJỌBA AIYE (Apa 1)

**Lati Owo Omọ – Oba Adakẹdajo**

O ṣe mi ni anu pupọ lati ma ri Işubu awọn enia ti ẹ ka si pataki laye, ṣugbọn ko ya ni lẹnu lati ri b. nitoripe mo mọ daju pe ohun gbogbo lo ni ere tirẹ fun ileri si ọrọ mi a mi ẹmi Otitọ mo fẹ ki ẹ wo iwe Irohin Imọlẹ ri ọjọ ọjọ 'Bọ ti iṣe ọjọ kejileiogun oṣu kẹrin ọdun to kọja eyiti akọle rẹ sọ bayi pe: "Aiye ko nipẹkun ṣugbọn ti o ba ka siwaju si Iwọ yio ri wipe a tun kọ sinu iwe "Ọjọ nbọ ti ẹ mọ Baba Alagbere baba nla wọn ko ti lẹjẹ ere ọmọ, a ti ki ẹni;l;ni ma lo ọmọ wọn bi omi ojo.

Jọwọ wa iwe yi ri tabi ki o bere lọdọ awọn Olutẹwe tinte Irohin Imọlẹ ki awọn tun tẹ fun nyin. Asọtẹlẹ oṣu mẹsan pere ni O k u t a ti nwọn fi nkọle kọ silẹ on lo di pataki igun ile ọjọ alẹ ni o ma nye Oluku .da ere nbẹ fun olukuluku, Iwọ to fi gbogbo ara ṣiṣẹ ti ọga ko yin, maṣe rope a ko ranti pe igba kan tun nbọ ti Iwọ yio fi ile ọga silẹ, ọga ki fẹ ki ọmọdọ kuro, wọn fẹ ma jẹ aiye lọ titi ọjọ ẹsan nkọ? tabi iwọ ko gba omialra lọ dọ ọga ki o to maṣe ọga? Ọlọgbọn kan ko le ta koko omi sibi ti Adakẹdajọ ko jẹ o ..orao kan ti a ko fi aye fun ko le mo iṣẹlẹ ti o nbọ ohuuti baba ko ṣe silẹ o mo ko le ba ohunti a bi ṣe laiye ere rẹ a ki gbin yọ a ki rọ nile alagbẹdẹ ko idabi etu ibọn ohunti Adakẹdajọ tiṣe ni, ṣugbọn iwọn laijẹ iyọ to pọ lọbẹ, ko si adun m., ohun gbogbo lo ni iwọn aṣẹṣẹ ma sinmi aisan lere rẹ.

IKU LERẸ AGIDI

Aye ko ni pẹkun ṣọra ki o maṣe jẹ aiye ni lijẹkuje tio ba jaiye bo tiṣe wa o, eyiti o ni aiye yio bere lọwọ rẹ ta ni yio mu mi? Ṣebi iwọ ko ti ẹlẹṣẹ ti o maṣe di ẹnikẹni ninu aiye ti o wa o si da mi loju pe abere yio si bere lọwọ rẹ

Tete rona piwada lati ma d'ẹsẹ nitori ere rẹ ko da ra iba maṣe pe a ti le Lusifa kuro ti ni ọrun iba ti gba



Ọmo – Oba Adakẹdajo

Ijọba Itẹlọrun ti gbogbo ẹda nlepa l jojumọ ṣe Lusifa loni oju kokoro eyiti ẹnyin ẹda ope ni oju kokoro. Eniti a ni ki o wa jẹun ti o f. awo onjẹ mọra ṣe ko kunkun lẹ ki ẹlomiran j un mọ, mase gbagbe pe ẹni— ka tun wa to bu uju mọ nigbati eleyi ba de iṣobu ikẹhin yio buruju ti isiwaju lọ

Nigbati mọ pẹlu enia ba nrin lọna mi iṣe ro pe mọ ni o pọju ninu awọn ti nrin lọ ni ọna ranti pe awọn ero kan ti lọ siwaju rẹ ati pe awọn ẹlomiran tun nbọ lẹhin rẹ iru fẹ ẹda ti o ti lọ si aju rẹ ni Iwọ ko mọ.

Ṣugbọn ẹ ni nsọ fun ọ gẹ gẹbi orukọ mi a ni otitọ mọ pe ero ẹhin pọ nwọn si ni agbara ju awọn ti isiwaju lọ. Otitọ ni ọrọ ti mo nba nyin sọ, ṣugbọn ẹda gbogbo ko le gba nitori nte ere iṣẹ wọn kiakia' ṣugbọn ẹniti opin ere l iṣe ẹniti a le pa aṣẹ fun kini ohun t o kere ki kọkọrọ ninu odin dini i e? kini ero t nbọ lati ode ko gbọdọ ṣe alani ọpọlọpọ ko mọ pe kọkọrọ ni owe ni eyi jẹ fun nyin, ṣugbon mo mọ pe igbagbo ti tan laiye o ku die mo bẹ nyin ẹ toju wọn ba to ko laiye ki ẹ şi dawọ duro lati ma le ohun aiye kini ere ọba ti ko ṣe rere ni gbati o wa lori aye ti ko si bi ọmọ silẹ ki o to fi aiye silẹ ootọni mo sọ fun nyin ọ an iun wa toju ọmọ lọ 'Iya ju wurn baba ni jigi oruk rere san ju ọr aiye lọ" ẹbun diẹ ọpọlọpọ ọda lẹ ni lọ okele ti wọ jẹ ni iwọ yio po, ṣugbon otito fi nyẹni bayi pe iwo yio poju eyiti iwo jẹ nigbati ẹlẹsan ba de.

Tani ẹniti ogun ti oju rẹ ja ri? Bi okun ba de ohun gbogbo ti a ti se ki ogun to de wọ ile ti a ti ka nigbati igbọnju nitori a fi eru gba ibukun ogun pa ọmọ ti o bi nigba ọdo to ti ga toni ni iduro nitori oju kokoro, ogun pa iyawo ti a fẹ ni owurọ kutu nitori agidi gbo ngbo diẹ ṣegbe lairo tẹlẹ ni tori ailanu rogbodiyan ipa nia de si ilu itori ẹnikan ṣoṣo iṣẹ ati wahala de ba gbogbo aiye nitori igberaga nyan airotẹlẹ wọ ilu nitori ọkanjuwa ọpọlọpọ lọ ku ni tori aimọkan wọn ti ẹtan gbe wọn si ọrun apapandodo eyiti o mu nini ile to run jẹki ọlọla ṣegbe ọba ti ade silẹ o tun wa pa ẹja lodo awon to nta ẹja ko kọ lati ta ẹja fun u, ṣugbọn ojukoroju sọ ọba Alade di ero odo apapandodo iṣẹ ti ko kọ ri to fẹ ṣe, a gbagbe pe awọn apẹja ti a yan wa lo lọ toto rẹ o ojukokoro ti npa ọmọde on na tun pa agba o pa ọkunrin o tun pa obinrin o pa Balẹ o tun pa Ikeji ilu on na lo pa Erelu obinrin ati Alhaji to lọ si ilẹ mimọ o tun pa Alhaja to tun ku iku kanna lo si pa wọn ṣebi iku ojukoroju lo pa Alufa to di ero ọrun, eyiti ko ku wa lọgba ẹwọn

Bakanna nwọn tun njadu oye Bişọba ṣeb ọkanjuwa kanna ni nwọn fi de Alufa Ta aka to nj le iku ebi lo pa ti nwọn ba mu ewo ni olowo to tun ji owo Talaka ṣugbọn iyanu kosi fun awọn ọmọ Imọle nitoripe nwọn ti mọ pe ọlọrọ toni ki okan majẹ mamu o ti daju pe asi ko rẹ ti to: Fi eyi kogbon itan itẹlọrun ni mo ti yo, Bere ao fi fun nyin Mathew ori keje ẹsẹ keje

IWE KOŞEMANI NI EYI

IWE ITỌSẸ OHUN GBOGBO
NINU ODU MẸRINDINLOGUN

Iwe yi kun fun Asọtẹlẹ ati wipe, yio din ọ lowo YẸMIWO" ku, nitoripe iwọ na yio le ma da ṣe AYẸWO fun ara rẹ
KOSEMANI" ni Iwe na, 2/6d pere ni a nta:-
Postage 9d

ẸSAN KOGBOGUN SERVICE
8, Idumagbo Avenue
Lagos Nigeria (Leti Ọja Jankara)

# Iwe si Olotu Irohin Imole

OLOTU IGBAGBOSE

## Ọlopa Ẹ Ran Wa Lowo O

Olotu jo wo gba mi ni aye ranpẹ ninu iwe nyin to kun fun ogbon ati oye lati kesi awon oga agba Ọlopa ni ẹkun Ikoja lati ṣe iranlowo fun awa enia to ngbe ni agbegbe Mushin ati Ọlorunṣogo lati le ma fi Olopa si oju ona Olorunsogo nibiti awon moto Bolẹkẹja ati Moluẹ ti nduro eyiti yio jẹ iranlowo fun awa obi ti omo won wa ni ileẹkọ ati pe ki nwon si ma se itoju awon omo ile ẹko ti awon moto wonyi ba fẹ duro.

Eleyi jẹ ohunti o lewu pupọ fun awọn ọmọ ile'ẹkọ ti nwọn jẹ ọmọ de lati le fo oju ọna na kọja ati pe bi Ọlọpa ba wa loju ọna na yio jẹ iranlọwọ pataki fun awọn Obi.

Asiko meji lo jẹ pataki fun awọnỌlọpa lati le ma duro si oju ọna na eyiti oṣe ni Owurọ ati ni Ọsa nigbati awọn ọmọ ile ẹkọ ba jade nitoripe are ti awọn mọto wọnyi ma nsa ko dara rara ati pe inu wa yio dun bi ọga awọn Ọlọpa ba le ṣe iranlọwọ yi fun O otu mo dudẹ fun aye ti ẹgba mi ejinde yio ma jẹ fun nyin O,

Emi ni
S Owonifari
MUSHIN

Ọpọlọpọ awọn ọmọdekunrin wa ni o ṣẹṣẹ jade iwe mẹfa tabi jubẹ lọ ti nwọn ko ri iṣẹ ṣe paa pa julọ ẹle ati awọn Ọlọsa pọ ni ilu Eko nitorina ewu wa fun awọn ọmọdebinrin ti ẹ nfi nṣẹ agbowo ninu Bọọsi Ijọba Munisipa

Nitorina mo kesi ẹnyin Alaṣẹ Ijọba Ibilẹ Eko (L M T S) bi Ọgbeni Ganiyu Dawodu, Alhaji Masha, ati Ọgbeni Tsoridi Lbwal ẹ ba wa wa iṣẹ fun awọn ọdọ nwonyi ki awọn ye rin kiri ilu

Emi ni
Jimọh Adedeji
EKO

## Ijoba Ibilẹ Ẹ Fi Eyi S'ero

Olotu, Inu mi yio dun pupọ bi ẹ ba le gba mi ni aye ranpẹ yi ninu gbajumọ iwe rẹ Oloyinmọmọ lati kesi awọn Igbimọ Ijọba Ibilẹ-Eko nipa awọn ọmọdebinrin ti nwọn gbe si aye agbowo ninu Bọọsi Ijọba Ibilẹ Eko,


Alhaji A. F. Masha

## Irohin Imọlẹ Ku Ewu O!

Mba ṣọpẹ bi Olotu iwe Irohin Imọlẹ ba le gba mi ni aye lati ki awọn alakoso iwe Irohin Imọlẹ ku orire nipa aṣẹ ti Ijọba Ologun ilẹ Naijiria pa pe ki a ma ka Irohin Imọlẹ nibikibi ni ilẹ Naijiria.

Ni nkan bi ọdun to koja lọ yi ni Ijọba ibilẹ kan ni awọn ilu bi melo kan ni Ipinlẹ Iwọ Orun ṣe ofin pe Irohin Imọlẹ ko gbọdọ wọ ilu na mọ ati pe awọn enia ilu na ko gbọdọ ka mọ, ṣugbọn nigbati Ijọba bọ si ọwọ awọn ọmọ Ogun ilẹ Naijiria labẹ Ọgagun Aguiyi Ironsi, o paṣẹ pe ki o fi yẹn kasẹ nilẹ ki ẹnikẹni to ba si wu lati ka iwe na ma ka laiko si ibẹru ta bi ojo pe ẹnikan yio mu mi

Mo ba Irohin Imọlẹ yọ, o ku orire, Iwaju ni iwe na yio ma lọ o

Emi ni
Adetunji Adewale
Ila Ọrangun

## Kere O

Njẹ o ti ni ninu "IWE ITAN ODUDUWA toṣẹ ṣẹjadẹ?

Ha! Kosemani ni iwe ni jẹ fun ọmọ Yoruba Iwe na kun fun itan Iṣẹdalẹ Yoruba, Kedere ni aworan Oduduwa ati ti ọmọ rẹ han ninu rẹ.

Maṣe jẹki nwọn rohin itan ilu rẹ fun ọ
3/- pere ni. Postage 9d

Tete fowo tirẹ ranṣẹ si:-

ẸSAN KOGBOGUN SERVICE
8 Ilumagbo Avenue Lagos Nigeria

GBOGBO ARA ILU NKỌ ORIN IYIN ATI OGO

NIPA **DYNAMIRE N** TỌNIKI



ALE-IBI-ALE Egbogi Tọki amọnu, titun ti gbogbo ara Ilu Eko ati jakejado Naijiria mọ daju ... Agbara ati Ajẹbidan ṣe lara agbalagba Ọkunrin ati Obinrin gbogbo

Bi arẹ ara ba nmu ọ, ni gbakugba fun wahala tabi iṣẹ ṣiṣe ti o ko le jẹun dara dara, tabi ki o male sun dada de ọkan lọsan tabi awọn ṣan ara rẹ gbogbo ki ṣe fun daradara ti Emi Breath Inu ko ba kunlẹ daradara wọn iṣẹ tabi wahala sise tabi inu awọn ailera gbogbo nyin ti ọjọ ori (age) ba ti kọja ogbọn ọdun si adọrin tabi jubẹ lo mọ daju pe DYNAMIREN ni egbogi ti o nfẹ lati sọ ara rẹ di ọtun ... pata oju rẹ yio si walẹ ... kete alafia ati Igbadun de Bere Dynamiren yi ni Ṣọbu awọn :-

Waterloo Medecine Stores
8. Palm Church Street P O Box 333 Lagos
LAGOS ISLAND CHEMIST
Nnamdi Azikiwe Street, Lagos
UNITED DRUG CHEMIST
Alli Street, Lagos.
ADEDUN CHEMIT
14, Wakeman Street
ATI NI ṢỌBU
IṢẸ OLODUMARE DISPENSARY OKE BỌLA
IBADAN

BERE FUN OJULOWO EGBOGI —

## "Congreve's Iodo Form--Oinment



Atamataṣe ni egbogi" ADIBLEGBO" yi ... fun itọju gbogbo oriṣiriṣi "EGBO—ẸSẸ" ni kiakia bi o ti wu ki jọ rẹ ti le pẹ to, Adiẹlegbo yi ko ni ẹgbẹ nitoripe wipe awa ko dọti ni bi ẹri gbogbo ti ba wa loja egbo patapata jade oju re yio si mo daradara. Lẹhinna oju egbo yi o ba jin sinu yio jẹki oju re hu wa soke, yio si pọn daradara tun bakanna ko si mọ werewere ni yio si san patapata Alafia de si ọ niyen : —

Ri daju gbangba wipe awon sobu ti a da oruko won abssale iwe yi ni ogbe ranṣe lọ ra. Bibeko awon Elero hii on ijibiti yio ta 'Adamodi' re fun o maṣe gba ra ... u

Waterloo Medicine Stores
8 PalmChurch Street Lagos
22878 Lagos Nigeria (Ojo Ifa Fanji)
UNITED DRUG CHEMIST
Alli Street Lagos
NIGERIAN MEDICINE STORES
Tinubu Square Lagos
LAGOS ISLAND CHEMIST
Nnamdi Azikiwe Street Lagos

# Ojulari A Ko Ri Okan

## Lati Owo Olanrewaju Ikęja

Nigba kan awọn ọrẹ meji kan wa ti nwọn fẹran ara wọn ti o jẹ pe nwọn ko bi ri ara wọn. Nwọn ko le jẹun oruko ekini nje ... ekeji nje Ọmọ-wumi awọn mejeji si ni iyawo kọkan. La pẹ ọjọ Ọlọrun gbọ adura Ọmọ-wumi iyawo rẹ loyun ... ti o ri pe iyawo on ti oyun inu rẹ ti dan o ti sare lọ si ile ọrẹ rẹ.

Ngbati o sọ fun Owo-wumi wipe Iyawo on ti loyun nse bi inu Owo-wumi bajẹ Siwaju ki iyawo Ọmọ-wumi to loyun o sọ fun ọrẹ rẹ wipe enia ko le wa laiye yi ti o ba ni owo ti ko ni ọmọ ko s... yio ... rẹ ni ọjọ ti o ba ku, ... owo ko le da gbe lọ si sare.

Şugbọn ... ọrọ yen da ... silẹ l... ara wọn Ti o ri jẹ pe Owo-wumi sọ fun un pe ti ... bi mi pe on ko wa owo nse ni oluwa ko ... lori ni ... Sugbọn ... yowu ti ... wa ki o m şe ... Ọ ... gbọ nkan ti o ... şo.

Ki a ma fa ọrọ gun nigbati Owo-wumi ... pe iyawo ọmọ-wumi ti loyun nse ni inu rẹ bajẹ nitoripe Iyawo ọmọ-wumi ti loyun ... pe ọrẹ on ma ... on bimọ bẹni iyawo mi ... ni oyun on ko tun ni owo lọwọ. O wa bẹrẹ si ronu ninu ile rẹ ni ọjọ kan pe, Kini enia le şe ki o to ni owo lọwọ o? O ba ... ti ... ngbati o de ... gbogbo ọrọ ... rẹ. Adahunşe ni ko si ... ki o ... tọju obinrin aboyun kan wa.

Ọmọ-wumi ... wipe ... ko şoro o ... yio tọju rẹ fun ... ki Ọmọ-wumi ba pada si ile pẹlu inu didun o bẹrẹ si ... ngbati o di irọlẹ ... yen o s... fun iyawo

IYO ... DI ỌLA

YẸ IRAWO RẸ WO

AQUARIUS (Jan 22 - Feb 20) Awọ ni tire ni gbo gbo ... pẹlu ara ... kosi ohun kan ... dam... rẹ

PISCES (Feb 21 - Mar 20) Tan gbogbo nkan ti o ti nşe bẹrẹ ni irin ... ti aw... enia yio ... fi şọrọ rẹ, yo da fun ọ loni

ARIES (Mar 21 April 21) Maşe fi ọwọ le ohun tuntun kan ti iwọ ko şe ri ero ti nwọn ngba si ọ ni pe ki a ... fun ọ lọrun

TAURUS (April 21 May 20) Aisan kekere kan yio ba ọ ja şugbọn si fi ... yio ... ki o ... işalẹ

GEMINI (May 21 July 21) Maşe lọ fi ọwọ fa ija gbọn wa ba ara rẹ ki o ... ni ...

CANCER (June 22 July 22) O ni lati wa akọkọ pataki lati ... wa ... rẹ loni ... vi ... si ri işe şe

LEO (July 23 Aug 22) Tẹtẹlẹ gbogbo nkan d dara ki ... o loni şugbọn ... maşe ... re loni

VIRGO (Aug 23 Sept 22) Iw... yio si ri oju rere ọrẹ ... to ... o ko ni ... lallai.

LIBRA (Sept 24 Oct 23) Obinrin ... kan yio ba ọ ... mura si ọrọ na yio di iyawo rẹ

SCORPIO (Oct 24 Nov 22) Ina rere rẹ si awọn enia yio ... owo ... fun o

SAGITTARIUS (Nov 23 Dec 21) Am... di kekere kan yio şe ọ ma ... fi ara si ... ma si şe jẹ ... wahala ... şe ni lwonlanw...si

CAPRICORN (Dec 22 Jan 20) Lo şora ... okun rin ... ohun ti ... opurọ ni gbogbo ohun ti o nlọ ni yio to ọ lọwọ,

# KERE O

ẸNYIN ỌMỌ ODUDUWA
"ỌBA ATẸRẸKẸ KAIYE NAI NYIN"
PẸLU ỌPA AJAŞẸGUN RẸ



## Oba Alaiyeluwa Oduduwa

Ẹ ku ọdun Ẹ ku Ajọşẹgun, Ile ko ni le ... yin, Ọta ko ni na nyin, Ajọde ara yio ma ... fun nyin.

Ẹ mura lati di ọpa Asia Ọ... Yoruba mu, Ẹni to tun ... tẹ bi ẹni Fẹ'ta, ... Tẹ... ero bi Agogo, O le ọta lugbọ, O le oşi danu, o ... Nigeria ... kan balẹ.

Nje o ti ka nipa itan Igbesi aiye Oduduwa ati ti awọn ọmọ rẹ ?

Maşe jẹ ki nwọn wa rohin rẹ fun ẹ, "Koşe mani" ni kan inu Iwe na jẹ fun Ọmọ Yoruba ... lo ra tirẹ toto tan 3/- pere ni, Postage 9d

F'owo tirẹ ranşẹ si.—

ẸSAN KOGBOGUN SERVICE
8 Idumagbo Avenue Lagos Nigeria.
...



IMOLE ORE AIYE TENI GBOGBO LAWA

NO 1,695 FIRDAY FEBRUARY 11, 1966 (2D

## Enia męta ku ninu ijamba moto

JOS. Gbogbo enia to nkoja loju ọna Bauchi si ọna Jos ni o bęrę si sọkun kikoro nigbati nwọn ri oku enia męta kan eyiti dęręba moto to pa awọn enia si pelu awọn enia to ku ti gbogbo ara awọn enia męta na kun fun ọgbara ejẹ lori moto kan to dojude ni ogun ibusọ si ọna Bauchi si ọna Jos Ipinlę Ariwa Naijiria eyiti o ję pe lęsękęsę na ni awọn enia na si ku ninu opin ọsę to kọja lọ yi.

Ninu ọrọ onimọto na fun oniwe irohin wa ni ilu Jos ni o ti ṣe alaye pe nigbati Diręba mọto na ko le ṣe ọna bi yio tiṣe dara mọto na eyiti o jẹ pe mọto na ti sare kọja aala ti mọto na fi lọ fori lu igi nla kan to wi ni ẹba ọna na.

Ọkunrin to ni mọto na tun ṣe alaye siwaju sii fun oniwe irohin wa pe nigbati Dirẹba na ko mọ eyiti on yio ṣe ati pe ẹru si ti ba ni o ba lọ fori mọto na lu igi nla na eyiti mọto na fi doju bolẹ ti enia męta eyiti Dirẹba mọto na pẹlu ku lẹsẹkẹsẹ ti mọto na fori lu igi nla na.

Awọn ọlọpa ti gbe oku awọn enia męta to ku ninu mọto na lọ si ile iwosan lakulaku ti ilu Jos lati lọ ṣe ayẹwo wọn. Awọn ọlọpa si tun ṣe iwadi ounti o fa ijamba mọto na bayi.

# ỌKUNRIN KAN SA ỌRẸ IYAWO RẸ PA

ILỌRIN:- Ọrọ di pẹnuka, gbogbo enia si bẹrẹsi sare ọlọmọgbọmọpọn nigbati ọdaran kan, Alfred Okpa, ẹni ọdun mejidi lọgbọn sare wọ inu ile itura kan ti nwọn npe ni "Niger Hotel" lọ ti o si lọ ṣa obinrin kan lada ninu ile na ni ọjọ ọjọ'Ru ti iṣe ọjọ kẹsan oṣu yi.

Ẹniti ọrọ na ṣe oju rẹ ṣe alaye fun oniwe irohin wa wipe, nibiti awọn enia na ti ngmu ọti lọwọ ni ọkunrin na sare wọ inu ile de, ti o si bẹrẹ si ṣa iyawo ile na ni ada.

Were, igbẹ la fẹ ewe, oko la fẹ ilasa, ni gbogbo awọn enia ti nwọn wa ni inu ile itura na ba ba ẹsẹ wọn sọrọ, ti nwọn si bẹrẹ si maa sare jade ninu ile.

Ọkunrin na tun ṣe alaye siwaju ninu ọrọ rẹ fun oniwe irohin wa wipe, nigbati awọn enia na ri bi agbara ẹjẹ ti ṣe nṣan ni ilẹ nibiti nwọn gbe ngmu ọti, were ni nwọn ba sare kuro ni idi ọti ti nwọn ngmu ti gbogbo wọn si sare fo oju ferese jade ninu ile na, nibiti obinrin na ti nyi ninu agbara ẹjẹ.

Ṣugbọn awọn enia kan ninu awọn enia na ko jẹki ọkunrin na sa lọ nwọn si tete yara ragabu rẹ ki o to sare jade ninu ile na.

Nigbati awọn enia bere ọrọ ohunti o de lọwọ ọkunrin na, ọdaran na ṣe alaye wipe, ọrẹ iyawo on ni obinrin na iṣe, ṣugbọn lati igbati obinrin na ti bẹrẹsi maa wa iyawo on wa, ni on ko ti gbadun iyawo on mọ, ti iyawo na ko si tun gbọ ọrọ si on lẹnu mọ nigbayowu ti on ba nba iyawo on na sọrọ ninu ile.

Nigbati on si se akiyesi iru iwa ti iyawo on na nhu mọ pe akiyesi obinrin na ni gbogbo awọn nkan ti on ri, on si tun se alaye fun ọrẹ iyawo on na wipe, on ko fẹ ko tun ma wa iyawo on wa mọ, bẹẹni ki nwọn maa se ọrọ mọ pọ̀u.

O tun si fun ọrẹ iyawo rẹ na wipe, nwọn le maa lo pade ni ode, ṣugbọn on ko fẹ ki ọrẹ na maa wa iyawo on wa si ile mọ gẹgẹbi o ti nṣe tẹlẹ rigbogbo, ọkunrin na sọ wipe, obinrin yi ko gbọ gbogbo ikilọ ti on se fun ọrẹ iyawo on na.

Ṣugbọn nigbati o di alẹ ọjọ ọjọ 'Ru ti iṣe ọjọ kẹsan oṣu yi, ni on ko ri iyawo on ni ile nigbati on de lati ibi iṣẹ nigbati on si bẹrẹ lodo awọnara ile, ni on ba sọ fun on wipe ọrẹ iyawo on lọ wa si ile ti on ati iyawo on si jijọ lọ si ode.

Ọkunrin na sọ wipe, nigbati on reti wọn titi ti on ko si ri wọn ni on lọ si ile iyawo nwọn obi rẹ si sọ wipe ko si ọdọ awọn.

Ṣugbọn nibiti on gbe nwa awọn enia na kaakiri ni on ba ri wọn ninu ile itura na ti iyawo on ngmu ọti pẹlu awọn Ọkunrin miran, bi nwọn ti ngmu ọti, bẹẹni nwọn tun nba Okunrin jo, ti nwọn si ndimo ara wọn, ti awọn enia npa atẹwọ nigbati on wọ inu ile na lo wọ awọn enia na.

Ṣugbọn on mọ dajuwipe iyawo on ko ni ifẹ lati ma lọ si ode, ọrẹ rẹ yi lo fẹ ma ko ni ikokuko ati ise kuṣe gbogbo ti iyawo on nṣe, bi on si ti nso fun ọrẹ rẹ to, ko gbọ gbogbo ohun ti on nwi fun un rara.

Nigbati on si ba awọn mejeji nibiti nwọn ti ngba dun ara wọn ni on ba ti ṣe da sẹria nla fun ọrẹ iyawo on na, ki o ma si ṣe tun wa pe iyawo on lọ si ode mọ ni ojojumọ.

Were ni awọn enia ti nwọn wa nibẹ ba sare gbe Obinrin na lọ si ile Iwosan ṣugbọn nigbati nwọn yio fi gbe Obinrin na de Ile Iwosan o ti ku bamubamu.

Awọn Ọlọpa ti mu ọdaran Okunrin na lọ si itimọle nwọn si ti gbe oku ọrẹ iyawo rẹ na lọ si Ile Iwosan Lakulaku fun ayẹwo awọn Dokita.

A lero wipe Okunrin na yio farahan iwaju adajọ ni Owuro yi lati sọ ti enu rẹ bi nwọn ba si ti pari ọrọ na si eo tun maa gbọ ninu iwe Irohin wa.

### LATI OJU EWE KINI

Awọn ọlọpa nu to lọ si ile igbakeji Ajẹlẹ awọn ọlọpa fun Ipinlẹ na si ko awọn iwe kan jade ninu ile na ṣugbọn awọn ọlọpanu si ta ku lati ṣe alaye lori awọn ohun ti nwọn ko jade ninu ile na nigbati nwọn lọ tun ile igbakeji Ajẹlẹ awọn ọlọpa ti Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria na.

Lẹhinna ni a tun gbọ pe awọn ohunti awọn ọlọpa-nu na ri ko jade ninu ile ọga agba awọn ọlọpa na ko jẹwọ awọn ohunti awọn ọlọpa-nu ri ko jade ninu ile ọkan ninu awọn Minista fun Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiriẹ tẹlẹ.

Lẹhinti irohin yi de ile iṣẹ wa ni a tun gbọ irohin kan lati ọfu ile iṣẹ awọn ọlọpa ti ilu Ibadan pe Ajẹlẹ awọn ọlọpa fun Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ti nwọn ṣẹṣẹ gbe lọ si ilu Ibadan Ogbẹni E. O. Olufẹnwa yio ba awọn oniwe irohin sọrọ.

Oniwe irohin wa ni ilu Ibadan fi ye wa ae ni ọjọ Ajeti iṣe ọjọkẹfa osu yi ni Gomina Ologun tiIpinlẹ Iwọ Orun ṣẹ ofin kan eyiti ojade ninu iwe irohin ti Ijọba IpinlẹIwọ Orun eyiti awọn ọlọpa ti lọ mu ọmọ ọba D. A. Ademiluyi ti o ẹ Alaga ile iṣẹ idagbọsoke fun Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun tẹlẹ

# Ọlọpa Ri Bombu Ni'le Minista

## Lati Oju Ewe Kini

Bakanna ni awọn ọlọpa nu titun mu awọn Akọwe agba kan ni ile iṣẹ Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ni Ibẹ ọsẹ yi.

A gbọ wipe, gbogbo awọn ile iṣẹ Ijọba ykı gbogbo Naijiria ni Ijọba ni mo iye owo ti Minista kan ni o Banki ati iye ile ti Minista kan ni lẹnu igbati awọn bẹrẹ iṣẹ Minista.

Bi gbogbo awọn ẹ̀ro ni bı ti se ni alo eo maa gbọ ninu Iwe Irohin wa.

Printed and Published By Modupe Printing Press, ... Street, Lagos Phone 21985
... 25, ... Street, Lagos 11/2/66